# AILOYE FARISI KAN NIPA PE JESU JẸ́ ỌLỌRUN

**Luku 7:36-50**

**ẸKỌ 43 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Nitori ẹnikẹni ti o bère nri gbà; ẹniti o ba si wá kiri nri, ẹniti o ba si nkànkun, li a o ṣí i silẹ fun" (Matteu 7:8).**

**I Fifi Ororo Kun Jesu ni ile Farisi Kan**

1 Farisi naa pe Jesu wa si ile rẹ, Jesu si wa, Luku 7:36; 5:27-32; Ifihan 3:20

2 Obinrin kan, ti o jẹ́ ẹlẹṣẹ ti o ronupiwada ti a kò si pe si ibi ase naa wá lati juba Jesu, Luku 7:37; 19:2, 3

3 Bi o ti mu àyè irẹlẹ kan lẹyin Olugbala, o fi ijẹwọ irobinujẹ ti o jinlẹ hàn, Luku 7:38; Orin Dafidi 34:18; 51:17; 2 Kọrinti 7:10

**II Farisi Alaigbagbọ́ ati Owe nipa Awọn Ajigbese**

1 Boya Farisi yii, ti o kun fun ododo ara rẹ ti kò si loye pe Ọmọ Ọlọrun ni Jesu i ṣe, rò pe oun n ṣe E loore ni, o ka A si ẹni ti o rẹyin, Luku 7:39, 40

2 Farisi naa dahun awọn ibeere Jesu nipa awọn ajigbese naa bi o ti tọ́, Luku 7:41-43

**III Ibawi Olugbala fun Farisi naa, ati Idariji Kristi fun Ẹlẹṣẹ naa**

1 Jesu ba ẹni ti o gbà A lalejo wi fun ikuna rẹ lati ṣe itọju ti o tọ, Luku 7:44-46; 1 Peteru 3:8

1 Obinrin naa ninu ibinujẹ rẹ lai pete, o ṣe itọju ti Farisi naa kuna lati ṣe, Luku 7:44-46; Romu 13:10

3 Kristi fi idariji ati alaafia fun ọkàn ti ebi n pa, Luku 7:47, 48, 50

4 Ki i ṣe onile yii nikan ṣugbọn awọn alejo iyoku pẹlu ni wọn ṣe alaimọ pe Ọmọ Ọlọrun ati alaṣẹ ni Kristi i ṣe, Luku 7:49; Marku 2:10, 11

5 Jesu fi idi rẹ han ti a fi dariji obinrin naa ti a kò si dariji awọn iyoku, Luku 7:50; Johannu 3:14-21; Romu 10:9; 1 Johannu 5:1

## ALAYE

Nibo, ninu gbogbo iwe-kikà, ni eniyan ti le ri itan ti o mu ni lọkan to eyi ti ẹ̀kọ́ wa n sọ yii? Obinrin yii, ti o tọ Jesu wá bi o ti n jẹun ni ile Farisi yii, jẹ ẹlẹṣẹ ti o ti n nọga fun idasilẹ kuro ninu ọkan ati aya ti ikaanu on ibinujẹ ti sọ di wiwuwo. Ọna ti o tọ́ ni o gbà lati mu irora naa kuro – **o tọ** Jesu wá. Bi awọn ti n tẹle apẹẹrẹ rẹ laye ti kere niye to! Iye awọn ti wọn si n ri isinmi ati alaafia ti oun ri si ti kere to!

A kọ́kọ́ ri Jesu nibi tabili àse naa, bi O ti fi ẹgbẹ ti timutimu (gẹgẹ bi aṣa wọn ni ijọ wọnni) pẹlu ẹsẹ Rẹ̀ lẹyin Rẹ̀. Oju-ita ati opopo jẹ éleruku; onile rere a si maa pese omi fun alejo lati wẹ ẹsẹ rẹ, lẹyin ikini kaabọ ti o tọ́ si iru alejo bẹẹ. Ṣugbọn Simoni, Farisi, kò ṣe bẹẹ. Dajudaju, o fẹ mọ iru ẹni ti Jesu i ṣe; ṣugbọn nipa iwa aibikita rẹ o fi hàn pe oun ko ka Jesu si alejo ti o ni laari kan lọ titi. O ṣe e ṣe ki o maa ro pe ko ṣe nnkan kan ni akoko yii bi oun ba kuna lati fi iwa ọmọluwabi gẹgẹ bi aṣa wọn hàn. Ko ni ṣai wi pe "ṣebi Nasarẹti ni O ti wá nibi ti wọn kò mọ iwa ọlaju to awa ti n gbé inu ilu."

Ṣugbọn a o ṣe Ọlọrun logo a o si yẹ Ẹ si ninu ọkàn araye. Bi awọn miiran ti wọn ni anfaani nla nlà ko ba tọ̀ Ọ lẹyin, awọn ẹlomiran ti ko ni anfaani nipa ti ara to bẹẹ rara, yoo ṣe bẹẹ. Simoni sọ anfaani nla kan nù, ṣugbọn obinrin ti ko ni laari yii mu anfaani naa lo! O wọle o si duro lẹyin Rẹ̀ pẹlu ẹ̀ṣẹ rẹ ti n ba a lọkan jẹ́. O bẹrẹ si sọkun pẹlu ikaanu fun ẹ̀ṣẹ rẹ; bi o ti n ṣe bẹẹ, omije rẹ bọ sori ẹsẹ Ọmọ Ọlọrun Olubukun.

A fẹrẹ le ri i, nigba ti ọgbara omije ṣú bo o loju, bi o ti wolẹ lori eekun rẹ, ti o gbá awọn ẹsẹ ti wọn yoo fi iṣo oloro gún fun idariji ati iwẹnumọ rẹ mu. O mọ pe ko tọ́ fun oun lati wọ ibi ase yii wá, nitori bẹẹ bi ẹni pe o n ronupiwada fun eyi naa, o bẹrẹ si i fi irun ori rẹ nu ẹsẹ̀ Jesu, o si n fi ẹnu ko ẹsẹ̀ naa. A ti fi hàn pe o fi ogo rẹ gẹgẹ bi obinrin lelẹ̀ ni ẹsẹ Jesu nipa ṣiṣe bayii. Ede ti a kọkọ fi kọ Bibeli fi oye ti o jinlẹ ti o si kún ju bẹẹ lọ hàn nipa iṣẹlẹ ti o mu ni lọkan yii. O sọ fun ni pe o fẹnu ko ẹsẹ Jesu ki i ṣe lẹẹkan bi ko ṣe leralera. Lẹyin eyi o ṣi apoti oróró ikunra ti o mu lọwọ, o si fi kun Oluwa ati Olugbala rẹ lara.

Simoni ri gbogbo eyi, o si bẹrẹ si ro pe bi Jesu ba i ṣe wolii ni tootọ O yẹ ki O ti mọ̀ pe ẹlẹṣẹ ti o buru ju lọ ni obinrin yii, ko si yẹ fun un rara lati ṣe iṣẹ rere fun ọmọluwabi kankan. Simoni ṣe ohun ti ọpọlọpọ alafẹnujẹ onigbagbọ́ n ṣe loniruuru ọna lonii. O ṣiyemeji pe Jesu ni Kristi. Kò gba pe Ọlọrun ni Oluwa wa i ṣe. O gbagbọ́ pe Ọdọ-agutan Ọlọrun alailabawọn yii jẹ eniyan kan ti kò fi bẹẹ ju oun lọ. Oun kò tilẹ ka Jesu si ẹni kan ti O le ṣakiyesi iwa eniyan.

Ṣugbọn Jesu "gbọ́" bi Farisi agberaga yii ti n rò, nitori Ọlọrun le ri bi ọkàn eniyan ti ri gan an, kò si si ohun kan ti o pamọ loju Rẹ̀. Lati fi ipo ọkunrin yii hàn án, Jesu pa owe ajigbese meji ti a dari gbese wọn jì. Nigba ti a bi i leere nipa igbese ọpẹ ti eniyan meji wọnyii jẹ onigbese wọn, Simoni dahun daradara, o si ti ipa bẹẹ dá ara rẹ̀ lẹbi.

Simoni ti o jọ ara rẹ loju yii kò mọ pe a ni lati gba oun là rara. O kún fun ododo ara rẹ̀, nitori bẹẹ ifẹ ti o ni si Oluwa ko to nnkan. Ṣugbọn obinrin yii, ti o kún fun ẹ̀ṣẹ ati idalẹbi, mọ pe oun ṣe alaini iranlọwọ kan ti ẹda ko le fifun ni; nitori naa o tọ Jesu **wá – o ronupiwada, o gbagbọ́,** a si gba ọkàn rẹ̀ là, o si fi ọkàn imoore rẹ̀ hàn nipa bibu ọ̀wọ̀ ti o tọ́ fun Alejo ti a kò ka si yii. Ẹni kan ti sọ pe iyẹsi tootọ a maa ti inu ọkàn ti o ni ifẹ si gbogbo eniyan sun jade. Ṣugbọn Ọlọrun nikan ni o le fi iru ifẹ bayii fun ni! Ifẹ ti otoṣi obinrin yii fi hàn jẹ ki a mọ̀ dajudaju pe o ni iyipada ọkàn.

Jesu sọ ọrọ imulọkanle fun obinrin yii – ati si olukuluku onirobinujẹ ọkàn miiran, pe "A dari ẹṣẹ rẹ ji ọ -- **Igbagbọ́** rẹ gba ọ là; mã lọ li alafia." O yẹ ki oju ki o ti wa fun ironupiwada ati irẹlẹ ti obinrin naa fi han, ṣugbọn o ni ẹbun iyanu miiran ti o ju wọnyii lọ. O ni igbagbọ́ ti Farisi yii tabi ẹnikẹni ninu awọn ti a pe sibi ase naa kò ni. O fi han pe otitọ ni ọrọ wọnni ti a kọ wi pe "ẹnikẹni ti o ba gbagbọ́" ninu Kristi yoo ni iye ainipẹkun. Awọn alaigbagbọ́ Farisi kùn, ṣugbọn onirobinujẹ ti o gbagbọ́ yọ̀! Olukuluku ẹni ti o wà nibi ase naa ni anfaani kan naa fun igbala; ṣugbọn obinrin yii nikan ni a sọ fun ni pe o ri ileri ni gbà, ti "ogun aidibajẹ, ati ailabawọn… ati eyi ti ki i ṣá ti a ti fi pamọ li ọrun" fun gbogbo awọn ti o ba ronupiwada ti wọn si gbagbọ́.

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni idi rẹ̀ ti Jesu fi jẹ́ ipe yii?
2. Ki ni ọkàn obinrin yii ti ri gan an nigba ti o duro lẹba Jesu nibi ase naa?
3. Ero ti o wọpọ̀ laaarin awọn alafẹnujẹ Onigbagbọ́ aye isisiyii wo ni Farisi naa ni si Jesu?
4. Iru ero bẹẹ ha le ran Farisi naa lọwọ, tabi yoo di i lọwọ, bi o ba ṣe pe oun naa n fẹ igbala?
5. Sọ itan awọn ajigbese meji naa ki o si sọ idahun ti Jesu tẹwọgba.
6. Ki ni ẹtọ ti Farisi naa kuna lati ṣe fun Jesu, ta ni ẹni ti o si ṣe wọn?
7. Nipa aile yẹ́ Jesu si bi o ti tọ́, ki ni iwọ ro pe o jẹ́ koko ohun ti Farisi naa n wi?
8. Ki ni ṣe ti obinrin naa fi ri igbala – nigba ti o dabi ẹni pe kò si ẹlomiran ninu awọn alejo naa ti o ri igbala?